Ogun Ita'ja

E Polowo oja yin sinu Iwe Irohin Eleti-Ofe, Kia L'oja o ta.

ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

kiyesi Pataki

A fiwe y . ş e kede si awon Asoju iwe irohin Eleti Ofe kakiri agbaiye wipe, enikeni ti ko ba fi owo ti o fi je ranşe si wa, o pe lejo, ako si ni fi iwe irohin ranşe si enibe mọ.

VOL. XI No. 623. LAGOS, SATURDAY, MAY 9 — MAY 15, 1959. KỌBỌ MEJI (2d)

# Arun Yinrun-Yinrun Tun Nse Jamba Si Ni Oke-Oya

KADUNA. Gẹgẹbi ikede ọsẹ to kọja, irohin ti o de si etigbọ wa ni wipe arun Yirunyinrun ati Ilẹgbona bẹ silẹ şugbọn gọngọ ti nsọ nilẹ Oke-Ọya nisisiyi gẹgẹbi irohin ti a tun ri gbọ, wipe o di enia meji-le-lọgọjọ ti o ti filẹ bora nipa arun Yinrun - yinrun na.

Iye enia ti a gbọ pe arun na ti ran lọ s'orun lọsẹ to kọja ni mejilelogoje şugbọn ti ọsẹ yi ti a gbọ tun peleke. Nilu Katsina irohin ti a gbọ nipe o le ni irinwo enia ti Ilegbona ti kolu, şugbọn ko si ẹniti o ku ninu wọn.

Nilẹ Oke - Ọya lapa agbegbe ilu Kaduna n Ilẹgbona ti şe ọsẹ ti o pa ọpọlọpọ enia. Işẹ bupabupa ti bẹrẹ nitoni pẹrẹwu ki arun na ma ba le gberan lasiko ayẹyẹ işe ijọba araẹni lọsẹ ti o mbọ.

## Oloye Enahoro Gbe Tit n De

Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Oloye Anthony Ẹnaharo ti o sọrọ ninu awujọ awọn Ọba ilẹ Yoruba wipe, ki o to to opin ọdun ti a wa yi, ao bẹrẹ si tan ina mọna-mọna alaworan ti yio ma sọrọ (Television) kakiri ilẹ Yoruba.



OLOYE ENAHORO

Awon ilu ti yio kọkọ je igbadun ina Onimọna-mona na ni Eko, Abẹokuta, Ijebu-Ode, Ibadan, Ikoyi (Ọbalende) Apapa Yaba, Mushin Agege ati Ikorodu Ọpolopo awon ti o ngbe Eko Abeokuta, Ijebu-Ode, Ibadan, Ikoyi (Ọbalende) Apapa, Yaba, Mushin, Agege ati Ikorodu. Ọpọlọpọ awon ti o ngbe Eko ni yio fi oju ri ero na.

Ijoba ko le şe kari gbogbo ilẹ Iwo-Orun tan lẹkanna ni akoko bẹrẹ yi, şugbon ijoba fi le okan wipe bi idiwo diẹ ti o wa nipa ẹro na ba ti kuro, ijoba yio şe de ilu Ibini. Nko fẹ ba awon enia Ibini lokan jẹ şugbon mo le so, fun won pe idiwo nwonyi lera. Eyin oje pataki niti ẹro işẹ na ti Ijoba apapoşe yio mu wa awon si ti ni meji nwọn si ni lati kọwe fun ẹketa ni.

Oloye Enahoro sọ wipe Ijoba Iwọ-Orun ni yio je asiwaju nile Africa ti o koko gbe ohun alarabara igbadun ti o kun fun eko bayi jade nile Nigeria. Ghogbo enia lo da muso rẹ lati gbọ ọrọ ti Gomina agba ilẹ Nigeria ki a to mọ ohun ti a le şe.

## Awon Arufin Npelemo Siwaju.

Awọn ọlopa fi ye wa wipe awon arufin tunbo npelemo siwaju. Lati ibẹrẹ titi de opin ọdun 1957, iye awọn arufin ti nwon da lebi ninu odun na le lẹgbaa mejila. Ni eşi, ti a rope awon arufin poju, aşe, nwon nşere ni, nigbana.

Ninu ọdun na, awon ẹru to sonu ati eyiti nwon ji lo, gbogbo iye owo re to £990,276.

Iye ẹjo awon apania ti nwon şe ninu odun na je 398. Ninu ejo awon apania na, enia mokanla ni nwon ti da lebi iku, ogbon enia ni nwon da sile, 357 ni iye ejo apania to si mbe nile lati şe

Ejo awon ti o şeşi pa enia ninu odun na je 356. Mokanlelogun ninu re ni nwon da lebi Merinlelogota ni ko jebi, 270 ni eyi ti a şi nro lowo.

Merindilogota ni ejo awon to fe pa ara won, ejo awon to ba ara won ja to 9823 awon ti a da ninu won je 4292. Iye awon ti o şe owo-eru je 76, ejo awon ajomoghe ti o wa je ogota enia mokanla ni nwon da lebi, ati enia mewa ninu awon ti o nse owo eru.

## ỌRỌ ILE-ẸKỌ ZARIA JADE NINU IG IMỌ ILU OYINBO

LONDON. Ọgbẹni Grimmond bere lọwọ Akọwe agba Ọgbẹni Lennox-Boyd, wipe bi o ti ri iwe gba lati ọwọ awọn oşişẹ ile ẹkọ na tabi koiti ri gba ?

Ọgbẹni Lennox-Boyd da lohun wipe on ti ri iru iwe bẹ kan gba şugbọn on tret

## Oku Ibeji Owo !



Owe ni esin oro. Yoruba l'o uso wipe "Bi oro ba sonu owe ni a fi nwa" be gege ni oro ti Ológhe Alhaji Adegoke Adelabu ti awon enia re n'ejo fun owo goboyi lati gba lowo onimoto to wa Adelabu lojo buruku esu gb'ono mu na.

Nigbati awon koko se ejo na ni kotu ni gba wipe ki Albert Younan ti o wa moto ni iwakuwa lọ san owo bi £6,135 fun awọn ebi Adelabu ati £685 fun awọn ẹbi Adeleke Arẹmu ti o ku pelu Adelabu.

Nisisiyi awon agbejoro fun awon ẹbi Adelabu ati Aremu ti kesi kotu ki o fi aşe si ki Albert Younan san owo na kiakia.

## Ọmọ Akẹkọ University Fe Fesi

IBADAN Lẹhinti awọn ọmọ ile ẹkọ University ti ka ẹsun sun Oloye Awolọwọ nipa ile rẹ ti o ngbe ti Oloye na si fesi da wọn lohun, ni ṣangba wa fọ ninu ile ẹkọ University na, tobẹ ti a gbọ wipe iwọn ọgọrin ọmọ ile ẹko yi tun ṣe apero, lati yan awon enia marun ti yio ro, kini ohun ti o tọ lati fi fesi, ki pa ọrọ ile ko ṣe 'le ti nwọn sọ pe Awolọwọ ngba ẹgbẹrin Poun fun.

A gbọ pe awọn bi mẹwa ninu awọn ọmọ akẹkọ na sọrọ ni ohun lile nipa esi ti Oloye Awolọwọ fun wọn, nwọn ni gbolohun kan ni nwọn bere lọwọ rẹ, ki o to wa da oporo ọrọ bo wọn toyi.

Ọkan ninu wọn tilẹ binu o mu iwe irohin Service, o ju sọtun ati si osi, o wipe opurọ ni awọn iwe irohin nwọnyi. A gbọ pe ọkan ninu awọn ọmo akẹkọ sọpe Họwu! ile elegba mẹdogun ko pọju fun Aṣiwaju awọn Oṣelu (Premier) kẹ !.

O si da ẹbi fun awọn ọmọ Akẹkọ wipe awọn enia wa ko nduro ro oro wo daradara ki nwon to mu ṣe niṣe Ọlọgbọn ni Oloye yi a ni lati ronu wo, ki a fi ero lu eto rẹ ki a to sọrọ si.

---

## AWỌN ỌMỌ ẸGBẸ SCOUTS TA OLOYE AWOLOWO LỌRẸ

IBADAN. Awon alejo kan, ti iṣe omo ilẹ Israeli wa bẹ ilu Ibadan wo, nwon si mu ẹbun omi odo Jordan ti a ti ngbọ okiki rẹ ninu iwe Bibeli ati iwe Bibeli ti a ko ni ede Gẹsi ati ede Heberu lati ilu won wa fi ta Oloye Awolowo lore.

Awon alejo na je Scouts aṣiwaju won ti o nje Ọgbeni A. Ran ko awon ẹbun na lo sodo Ọlọla Adigun lati ba won ko ẹbun na fun Oloye Awolowo.

Ọgbẹni J. Ọla Adigun Alabojuto iṣẹ ilera ti alafia ilu gba ore na o si dupe lowo won fun ore ti nwon ta Alakoso ijoba o si ṣe adura ki Ọlorun maṣe ba irẹpọ wọn jẹ.

---

## Ako Le Fi Oogun Lapalapa Wo Ete.

ABA. Agbo irohin wipe nipa oru ti o mu lasiko yi ni ilu Aba, pupọ enia ni ara ri su wuru, eyi d'eru ba awon enia boya arun soponna l o nfe sele.

Agbo lati o d o Olori ilera ilu pe enia ko le fi egbogi lapalapa wo arun ete. Arun ara sisu wuru yato si arun ilegbona gbogbo awon ara ilu Aba lo nsare lo ko nomba nitori ti i ara won su wuru.

Egbogi ara sisu wuru yato si ti sopona. Nigbati arun soponna ba nfe sele ni a ni lati bere si bupa fun gbogbo enia. A ko si le fi nomba kiko wo arun ara sisu san.

---

## K'ama Rin Lojo Tebi o P'ona !

EKO. Lalẹ ọjọ ọsẹ ti iṣe ọjọ kẹta oṣu May 1959 ni Mọto Munisiba ti o mba wọn ṣe iṣẹ alẹ, ti nwọn npe ni "Agege" lo ya bara wọ'le lọ pa ọmọ ekee bi ọmọ ọdun kan abọ mọ ori ibusun rẹ ni opopo Campbell, o si ṣe iya ọmọ na leṣe.

A gbọ pe iya to jẹ onile paapa f'ara gbalamọ nipa ogiri ti o wo lu mọ nibi ti o sun si. A gbọ pe awọn mejeji ti nwọn ko lọ sile alaisan ri alafia diẹ-die ṣugbọn nwọn koiti ri awamọto (Driver) to wa Mọto na mu, awọn ọtẹlẹmuyẹn si nwa lọwọ.

Lọwọ iku ojiji, Oluwa rere gba wa.

---

# Awolowo Gba Asikiwe Ni Imoran

Oloye Awolowo te waya ranse si Dr. Asikiwe wipe, on gbo pe o fe wadi wo, lati ṣe itunpẹpẹn nipa owo ti nwon lo gba jo ni agbegbe ila-orun (C. O. R. ) ati lati se ayewo (African Academy of Arts and research) ti o je wipe Dr. Mbadiwe ni Olotu ẹgbẹ na.



Bi aṣiwaju awon Oṣelu ni agbegbe Ila-orun, 'ba lero pe, aforiaforun, ayafi bi on ba ṣe iwadi ọrọ na dandan, o so pe, yio 'fun Ijoba-Iwo-orun ni agbara lati gbe iru ese kanna, si awon ẹgbẹ N. C. N. C. ti mbẹ ni agbegbe Iwo-orun.

Loju temi, emi koro pe ohun ti o dara ni lati bu iru iwa bawonni si awon alatako. Nitorina mo gba ọ ni imoran pe ki o mowo koro ninu iwadi na. Sugbon bi o ba so wipe dandan ayafi bi o ba se itunpepen na, ikilo mi si ọ ni 'pe ao gbesan iru rẹ lara awon ọmọ egbẹ rẹ to mbẹ nilẹ Yoruba.

---

ELETI OFE DARABA

# NISISIYI!

FUN IGBA AKOKO NILE NIGERIA ...

AWỌN ONIṢOWO

**THE NIGERIAN GAS CORPORATION LTD.**

YIO MA ṢE

ETO OHUN IDANA GAS SINU ILE LATI MAFI DANA

Ale fi Gas pẹlu Meter rẹ sinu ile ti a ngbe Koni agbekiri. Ko si ni ṣalai muna wa nigba kan. Ko lewu, o rọrun, lilo rẹ din inawo ku.

ẸNYIN KỌLEKỌLE, ONILE ATI ẸNIKẸNI TI O BA FẸ LILO RẸ KI

O KỌWE FUN ALAYE KIKUN LỌDỌ :-

**NIGERIAN GAS CORPORATION LTD·**

2, ITAPEJU AVENUE, P.M. BAG 1040 APAPA TELEPHONE 55295.

Iye owo rẹ ati gbogbo alaye nipa rẹ ni ao ṣe fun yin lọfẹ.


## Awon Olosa Dana Losan Gangan

ABẸOKUTA. Irohin kan wa wipe awọn ọlọṣa lọ dena de mọto Akero kan ti o nlọ si Eko lati Abẹokuta nwọn si juwọ si Onimọto na wipe ki o duro, o si duro ni awọn Ọlọṣa na ba bẹrẹ si ko ẹru. Obinrin ti o ba taku wipe nwọn ko gbọdọ ko ẹru on, nwọn o ṣa a ni ada

A gbọ wipe awọn Ọlọṣa na fi Kareta boju n·ori ki enia ma ba le mọ wọn Ko si si nọmba lara moto wọn. Awon ti nwon ṣa lọgbẹ ra pala wo inu igbo lẹhinti awon oloṣa na ti lo tan, awon cro oko na pada si Abẹokuta, nwon si lo fi oro na han awon olopa.

Awon olopa ṣi wa lẹnu iwadi oro na. Bi a ba ti tun gbo bi oro na ti lo, ao jẹki ẹ gbo.

## Awon Oyinbo Meji Se Faya-wo

MONROVIA. Irohin de si eti gbọ wa wipe awon oyinbo meji, Joseph Westriech, ati Albert Tarah ti iṣe ara ilẹ Belgium ni a gbọ wipe, nwon ti odidi, ihi won lohun wa ṣe fayawọ okuta Dayamon nilẹ awon Kurumọ, nwon si gbe ẹjọ awon enia meji na lo sile idajọ, Ogbeni Herbert Brownell ti o nṣe Attorney General nilẹ Amerika si lo wa ṣe agb'ẹjo ro fun awọn Onifayawọ mejeji.

Ẹsun ti nwon ka si awon enia na lorun ni wipe, nwon ṣe fayawo okuta dayamon olowo iyebiye £89,000. Ẹjo na ṣi mbẹ nikawo ijoba Kurumo, nwon nṣe iwadi lowo.

## Irin Ajo Lo Si Meka Ati Medina

Ki a to fi Jidda sile ao ti gbe Harami wa wọ, nitori enia ko gbodọ wo Mecca lai ko gbe Harami, ti a ba ti de Mecca ao lọ Tawaf lẹhin na ao sa ere Safa Moriwa, lẹhinna ao ma lo si Harami ao ma lọ ki irun wakati mararun ni ojojumọ, ti ti igbati ile Oluwa ma fi gbe Harami Tirẹ, nigbati Ile Oluwa ba ti gbe Harami, ao wa mo ọjọ Arafa nigbana. Kosi ẹni ti o le mo ojọ Harafa ayafi bi ilẹ Oluwa ba gbe Harami. Ki ile Oluwa to gbe Harami kẹ, Harafa ko ni ku ju ọjọ merin lo.

Bi Harafa ba ku ola ao wo moto, ao lo sun ni Minna. Bi a ba ti Kirun asuba ni Minna ao wo moto ao lo si Harafa. Harafa ni ilẹ yio mo wa si.

Harafa je ilẹ to tẹju gegẹbi moshalasi wa ni Eko (Lagos) ko nse wipe Harafa ngbe enia lo si oke rara, ilẹ pẹrẹsẹ ni, ao pagọ kakiri ero yio pọ pupọ. Enia yio pọ tobe to fi jẹ wipe ayafi ọjọ Ajinde ni enia yio to tun ri iru rẹ. Ao wa ni Harafa yen titi ti o ba di dede Hayila, a ko ni ki irun yen, sugbon ti o ba to dede alasari, ao wa ki Hayila, ti a bati salamo Hayila tan, ao tun ki alasari ni ẹṣe kanna.

Bi a ba ti ki tan ao ṣe adura, wa tọrọ gbogbo nkan ti o ba fẹ lodọ Ọlọrun. Irun ti a nki ni Harafa yi, ko nṣe wipe a nki gegẹbi a ti nse kirun ọdun tiwa nibi rara. Iba ẹnyin ti ẹ ba wa ni "Camp" tiyin ni Mutawaf yio ma ki irun fun, awon ẹlomiran Mutawaf won yio ki ti won fun won bẹ bẹ ni gbogbo yin ma ki irun yin ni ọtọtọ bẹ bẹ.

Bi ẹ ba ṣe adura tan, Mutawaf yin yio wa mu yin lọ si idi oko Ganal Ramọt yio wa ke wutuba fun yin nibẹ. Bẹ ni awọn Mutawaf awon ẹlomiran yio mu awon na lo lehinna ẹ ti ṣe Harafa tan niyen, ao wa kuro ni Harafa, ẹ wa sun ni Musdalifa, nibẹ ni ẹ ti maki irun Halasari ati Ishai, lati Harafa si Musdalifa to iria buso mẹta, ti ẹ ba de Musdalifa, ti ẹ ba kirun Halasasi ati Ishayi tan, ao wa sa oko ti ẹ ma sọ fun Satan dani ni alẹ yen.

(Koiti pari)

# ELETI - OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI L'EJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM

28, Kosoko Street, Lagos. "ELETI - OFẸ LAGOS"

P. O. Box 467 Phone 23370

VOL. XI. NO. 623. SATURDAY MAY 9 - MAY 15, 1959


## Adura L'ebo

Ko si ohun meji ti awa eda enia owo Olodumare nilati ma fi ṣe iṣe ṣe lorekore, nini ile tabi lori ibusun wa, nibi iṣe wa, lori irin igboke-gbodo wa nile aiye yi ju adura si Ọlọrun Oluwa, Olodumare Ọba Ọgọ Ogo fun idabobo rẹ lori wa, ati ipe bi a ti ṣe na ti ndun yingba to yi, beni o si ya kiakia si ọna ọrun alakeji arembọ.

Ṣiṣọ ti Ọlọrun nikan lo'le gba enia la l'aiye wa yi, a ni ko si ibiti enia gbe le wipe on ni ifọkanbalẹ, ti ko si ewu niwọn igbati enia ko le sun sinu iyara rẹ ninu ile ki o fi ọkan balẹ lara ọganjọ, ki a ma ṣiṣẹ sọ ti ọsan ti gbogbo ẹrọ apanima-yọ'da nro giri-giri kakiri ilu aiye ọlaju wa t'ode oni.

A fi wosika wa yi kesi awọn aṣiwaju ẹsin wa, ni Igbagbọ tabi Imale, ki awọn jọwọ ba tẹwọ adura si Ọlọrun Olodumare, ki o fi iṣọ rẹ ma ṣọwa lọjọ tabi o p'ọna, nile, l'oko, l'odo ati nibi gbogbo.

Ki a maṣe lugbadi jamba Mọto, Basikulu ati Ọmọlanke. Amin, aṣẹ, bẹ ni kio ri.






## Oloye Awolowo Fesi Pada Fun Awon Omo Akeko University

Iye owo ti awon Premier mẹtẹta ngba lowo ijoba gẹgebi owo ile niyi. Ni Ibadan owo ti ijoba nna lori ile ti Aṣiwaju awon oṣelu ngbe (Premier) jẹ ẹdẹgbẹrun Poun (£900) Ni ile Hausa, ijoba nna adota-lẹ-legbeta Poun(£650) lododun. Sugbon ni Ila-orun, owo ti ijoba nna je ogojilelẹgbẹrun Poun(£1,040)



Oloye Awolowo so pe, on ri ka ninu iwe irohin Sunday Times ti ojo keta oṣu May, pe awon omo akeko ti o le ni ẹdẹgbẹrin ṣe igbimo ninu ile ẹkọ University College ni Ibadan pe awon Premier nna owo ijoba ni inakuna. Nwon so wipe awon ti fi ẹda iwe na ranse si mi, ṣugbon titi di isisiyi, nkoiti ri ẹda iwe na gba ṣugbon eyi ti mo ri ka ninu Sunday Times yi na to ere ṣe.

Ẹda oro ti nwon so ni ipade na ni Ibadan nihin ṣiwaju de Eko, ṣugbon koiti de ọwọ mi ni Ibadan, tabi ẹ ko roju aiye lode bayi ? Ko si inakuna kan ninu owo ẹgbẹrin Poun ti ijoba nsan lori ile ti mo ngbe, ki o le ye wa yekeyeke, ẹ jẹki a yewo, elo ni yio na ijoba, bi nwon ba fe ko ile fun ibugbe Olotu ijoba (Premier fun mi. inawo re le je £30,000, tabi £50,000, tabi £300,000. Sugbon ni ti emi, eyiti inawo re kere ni mo yan, eyi ni £30,000.

Nigbati a ba fi £30,000 ko ile ti on yio gbe, owo ti o dara lati ma fi se akojo owo fun ijoba, lati le ma lo fun ẹkọ ọlofe fun awon omo wa lọkunrin ati lobinrin, niṣiṣe bayi, mo din inawo ijoba ku bi ẹdẹgbẹrin Poun lododun ti a le fi ṣe anfani fun awon enia wa. Ohun kan ni mo tun fe fi ye awon omo akeko, ẹdẹgbẹrun poun (£900) ni iye inawo ti a ni lati ṣe lori ile Prime Minister, lori ile Minister inawo re jẹ adọtalenirinwo Poun (£450.)

Lona keji ewẹ, ko si otito ninu oro wipe mo ngbe ile mi nitori ati le ma gba £800 lowo ijoba dipo ki ngbe ile ijoba.

Bi o ba ṣe pe mo fe ma gba owo ilu lasan ni, mo mo ọna ti mo le gba ṣebe, mba jẹki ijoba ko ile fun mi ki nsi fi ile temi haya lo wo goboyi bi ẹdegbeta-le-legberun poun.

# NIGERIAN TOBACCO COY LTD.

**(INCORPORATED IN NIGERIA)**

Awọn Oyinbo Onișowo ewe taba (Nigerian Tobacco Coy Ltd) nfẹ awọn ti o ti mọ iṣẹ Fitter ti nwọn si ti yege ninu idanwo re ti ipo rẹ jẹ ekini tabi ekeji awọn ti o mọ iṣẹ nipa ẹrọ mọto, ki nwọn kọwe fun iṣẹ ninu ile iṣẹ ẹrọ wọn.

Awọn ti a ba gba sibi iṣẹ yi yio wa fun yiyẹ iṣẹ wọn wo fun ọdun kan, bi o ba si yege nipa mimọ iṣẹ na, ao gbe si ipo ifi ọkanbale (Permanent).

Owo ti nwọn o ma gba, ati aye iṣẹ wọn yio jọju.

Idanwo wọn yio gba ọjọ meji, awọn ti a ba si yan yio ri iwe wa gba.

Awọn ti o ba ni imọ to ni ki o kowe fun aye na ki nwọn si sọ iye ọjọ ori wọn, oye wọn, lakaye wọn, ni ibiti nwọn ti nṣe iṣẹ ri pelu iye owo ti nwọn ngba lọsu lọwọlọwọ ki nwọn fi ranṣẹ si :-

PERSONNEL OFFICER,
**NIGERIAN TOBACCO COY LTD,**
**P O. BOX 6, IBADAN**

Gbogbo awọn iwe ni ao yẹwo ni aṣiri, ẹnikẹni ti o ba si kọwe ki o kọ asiri sara rẹ bayi "Confidential". Fitters T.T. I. tabi II, Tabi Mọto Mechanic T.T. I. tabi II.

Ẹnikeni ko gbọdọ fi ojulowo iwe ẹri ti o gba nibi iṣẹ ranṣẹ ayafi ẹda rẹ gan-an. Ẹnikẹni ti a ko ba pe ti o ba wa, a ko ni da lohun, a ko si ni ba ẹnikẹni sọrọ nipa iṣẹ yi lori ẹrọ isọrọ (Telephone).

# Ipade Omo-lebi Ile-Oye Oluwa

Ipade pataki yio wa fun gbogbo ọmọ ile-oye Oluwa ninu Iga Oluwa ni Isalẹ Eko lọjọ Ọsẹ ti iṣe Ọgunjọ oṣu May, 1959 ni agogo mẹ́wa abọ Owurọ 8.30 (a.m.)

Ao ṣe ipade yi lati yan awọn igbimọ Alabojuto ti yio ma bojuto Iga ati gbogbo ohun-ini Ile-Oye Oluwa.

Ki ẹṣẹ gbogbo ẹbi pe.

**AKỌWE ẸBI**
**Ile-Oye Oluwa**

## IJUMU PROGRESSIVE UNION CONFERENCE

The Ijumu Progressive Union at a two days Conference held at Ilesha starting from Saturday 25 to Sunday April 26 passed a resolution to protest to the Northern Nigerian Government over the government decission to remove the Higher Elementary Course from the Women Training Centre from Kabba to kano The Union argued that there are some Institution in this Region where lack of adequate students and tutors contiributed to the non smoothing running of such institution.

It was stated that the Regional Government wanted to remove the Institution because Kabba is a hopeless Centre of Education. The Conference unamiously passed a resolution to those one mile radious of Iyora township as the new Iyora Headquarters for Administration purposes. Such Headquarters will afford the Government to build all their amenities there. Another resolution passed was that of Ijumu Grammar School of which £5000 was set as target. The Grammar School when completed will be the first Secondary male school in Ijumu district.

Other resolution passed are was the one to build a Town Hall and a Centre Court building at the new Ijumu Headqua-

(Continued on page 7)

# Iwe oko Ilu Barcelona.

Bi o ti jẹ wipe ilu Barcelona ko ju irin wakati meje pere lọ si ilu Kano ninu ọkọ Ofurufu ti B.O.A.C ti a npe ni Britannia, awọn ero ti o ba nfẹ duro ni ilu na nilati gba Iwe aṣẹ fun ilu Spain.

A le gba'we aṣẹ ero lọdọ Aṣoju ile Spain, Ọgbẹni C. Mondora to ngbe ile ti G. Cappa kọ si Iddo, l'Eko. (Tele : 24861).

ko si wipe a nilati gba iwe kan pataki ki a to ri Iwe aṣẹ na gba ṣugbọn awọn ero ọkọ nilati fi iwe aṣẹ ero Ọkọ (Passport) to ni aye ti ao fi ontẹ ilu Spain si ninu ranṣẹ.

A le fun wọn ni Iwe aṣẹ ọlọjọ meje fun ṣile mẹdogun (15/-) tabi ti aladọrun ọjọ (90 days) fun sile metadinlogbọn (27/-). fun alaye to piye, lọ ri Aṣoju B.O.C. tabi ti Nigerian Airways, ni ile ibiti nwọn ma ngbawe l'Eko, awọn ti o ma nṣe iranlọwọ fun awọn ero.

Iwe aṣẹ ọkọ ti a ba mu lọ fun wọn ni Nigerian Airways lati okere wa, ni nwọn yio dapada fun ero na larin ọsẹ kan.

Tirẹ nitotọ
V.F. Aherne
Ọga Oluta Oja. W.A.

**E MA KA IWE IROHIN ELETI - OFE**

# Ayinike Ati Ayinipada

(Apa II)

Lati Owo Ẹso

Nigbati o se ti osupa tun de Igba ti de ariwo nse ge-e, ilu ati orin ndonyungba, gbogbo ese awọn omo ẹranko pe Ologbo paapa ti de, o lugo si ẹgbẹ kan. Ṣugbọn Ikoriko pẹ lehin ki o to de. Bi o ti nsare bo ti o de ẹhin gbo ti o nnaga wo awọn ti o nja lọwọ, ori pe Aja ati Ẹta lo nja lọwọ, gbogbo eranko si nwipe gbe! gbe! gbe a yi fi gbi nile ti aja da Ẹta. Ni aja ba bẹrẹ si da orin bayi pe:-

Wo, wo, wo, o
Alumọ lumọ daiya
Wo, wo, wo o

Nibiti Ikoriko gbe nnaga lati wo eniti o da ara won, o sesi lo tẹ Ologbo mole. Inu bi Ologbo tobe ti o fi pe Koriko ni amukun, iru obu yi je ebu ara fun eranko. Koriko o si nse kitakita bo lati wa ba Ologbo ja sugbon Ologbo ni ki awon fi sile ki o ma bo wa tẹ.

Bi Koriko ti gbo oro abuku yi, .. re ru, o fere bo o loju, o wipe iru on Ikoriko si yanu Ologbo. Eyiti a nwi yi ti pe gbogbo irun ara Ologbo ti dide ṣugbọn nigbati nwon nla koriko ti o ko pe, ayafi bi on ba ba omo inu on ja, nwon bigbo fun awon mejeji.

Nwon 'wọya ija, Koriko rope agbara on ka ologbo, nigbati o ṣe ti koriko ki Ologbo molẹ o fẹ fi ibinu kia pa, o gbe roke rodo, o ju soke Ologbo dabun pe Ayinike beni Koriko subu lule, o si fi nan ṣẹ

(Koiti pari)



# Itan Elegbeje Ado

ILẸ OJỌ KEJI MỌ

Fee ti ilẹmọ ọba lọji alagogo rẹ lati lu agogo fun ara ilu lati wa gbọ irohin lati ẹnu Elegbejeado ni agogo mẹrin irọlẹ. Lẹsẹkanna alagogo gbe sita o si nlu kakiri Ilu, ki Ọkunrin, Obinrin, Ọmọde alagba, ati awọn alejo ila fi gbọ si eti.

Lẹsẹkanna ni gbogbo enia ti wa duro si afin ọba ibẹ ni ọpọ enia ti jẹun ọsan ni ọjọ na.

AGO MẸRIN LU

Ọdẹ elegbejeado de, osi ki awọn enia, lọkunrin lobinrin ọmọde agba ati awọn alejo ilu na paa. Oni mokiyin lọpọlọpọ ti kiki na ko ni opin on ti oju miri ni Igbo Ọṣudundun tan emi ko le fi ẹnu sọtan, Ọlọrun Ọba ni ko pa mi ati agbara awọn Iya mi Oṣoronga na pẹlu ati ori ẹyin ti eduro loni yi pelu Pataki julọ, Ẹbora Oṣudun na ni momu daniyi. emi yio si fi han yi nisisiyi ki gbogbo yin fi arabalẹ dada kie mase ja rara tori miko biki se agbara Edumare ati Olutanlowo

ỌDẸ ELEGBEJE TỌWỌ BỌ APO.

Ọwọ ti jagun fi bo apo Igbale (Ọwọ) lo mu jade gbogbo won fi ara balẹ won wo o won si ri igbale na gẹgẹbi on ti nmu hele-hele-hele ayа won ja oni ki olukuluku fi ara balẹ o gbogbo won si palolo lesekanna, jagun tun to wo bo apo lekeji o tun fa ado kan yo fifa to fa yo ona ado yi si igbale yi lesekanna Igbale na di Ebora Osudundun riri ti awon ara ilu ri nse ni nwon ndigbolo ara won fun ẹru biba Ọba papa mura lati fese fẹ kia ma fagun otun towo bo apo ofa ado kan yo si osi tun na ado yi si kiamasa Ẹbora yi ti da igbale pada ti on si nmi hele hele hele gegebi ti uele ri, lehinna na ni Elegbeje ado wa fi enu le irohin awon ara ilu oni ohun ti on ri on kole fi enu so tan ohun pataki tie si lati se nipe kioma dupe lowo Olorun ko si ohun to jubelo.

Ohun ti mo koko ri ni awon Ebora ti apa kan won je eranko ti apakan si je enia, awon yen ni Ebora inu igi nla, araba. Iroko ati ọpọ pelu awon ebora wonyi papa ba Ebora Osundun jati toje je o ma npa awon omo won je, awon papa mura lati pa mi sugbon ede ti won gbo lenu mi ki ran to fi mi sile lehinna ni nwon ran mi lowo nwon si fi ona ti mo le gba han mi. Ona ti won fi han mi na lose mi ni aufani loniyi, mo si wa jabo fun yin nigbati mo segun tan

(Koiti pari)

# Enia Kan Lo Moribo Ninu Enia Mokandilogun

EKO. Awọn ọmọ ẹgbẹ Odosi Obodo ti nwọn npa enia gẹgẹbi o ti wu wọn nilu Abakaliki, tiọwọ ijọba tẹ wọn, adajọ si paṣẹ wipe ki a yẹgi fun wọn. Awọn enia mọkandilogun ninu awọn ti nwọn ni ki a yegi fun na sọ pe ẹjọ ko tẹ wọn lọrun, ni nwọn ba gbe ẹjọ na lọ si kotu kotẹmilọrun tabi wipe nwọn lọ si kotu Arotunro.

Ninu kotu nla ilu Enugu ni adajo ti sọ wipe awọn enia na jẹbi iku dandan, nitorina ki a lọ yẹgi fun wọn, ayafi okunrin kan ninu awọn apania na ti oruko rẹ nje Agbo Openyi, ni agbejọro rẹ ta ribiribi nidi oro na pe Agbo Ọpẹnyi ko jẹbi ẹsun na.

Loya Ese ti o nṣe agbejoro fun Agbo Ọpẹnyi se gudugudu meje wipe, Ọpẹnyi lo lọ pe Okoro ti awon lu pa jade nile, ṣugbọn ko lọwọ ninu pipa rẹ. Nitorina Ọpẹnyi ko jẹbi, ni adajọ ba fa iwe ẹjọ tirẹ ya pe ko jebi iku. Ṣugbọn awọn yoku di pipa.

# Ese Ti Eyi Fi Je Be

Olotu,

Jọwọ gba mi laye lati mu ọrọ orin meji nwọnyi wa si iwaju awọn okawe rẹ boya ngo ri eni ti yio le fun mi idi abajọ ọrọ na Ọkunrin kan akọrin nilẹ awọn Ẹgba ti o nje Aribiloṣo kọrinekutẹ, on lo kọrin bayi pe B'obinrin dara pupọ lọwọ ọkọ A ma rin l'agan.

Ọgbẹni Ṣobọ Arobiodu, olorin Ẹgba miran bakanna lo tun kọrin bayi wipe :-

Bobinrin dara pupo a yagan,
Obinrin yi ba yagan,
Ko ni lomo nikun,
Obinrin yi dẹ npamọ bi'dun
Ko nidiri, ki iwẹ, ki ikun,
ko ni Ṣanju, ko ni torin benu
Ipi amala ba ti wa lọwọ ọkọ,
Ọpa ! bo ni wehin wo;
Iru awọn yẹn re mbimọ
Kagbọn ligba ọjo jojo.

Ibere mi niyi. Kini ohun ti o fa a ti nwon fi nso pe ẹniti o ba fẹ arẹwa lobinrin fe iyonu' Ki lo fa ti awon arewa obinrin ko fi mbimo pupo ? Ẹ fi ye mi.

Emi ni

Kẹhinde Agbassa.


E MA KA IWE IROHIN ELETI - OFE

LỌSỌSẸ OKUN FUN IROHIN ALADUN


# Ogunna Gbomgbo Meji Ni Yio Gba Alejo



Ẹniti a nwo yi ni Alhaji Tafawa Balewa ti iṣe Prime Minister ti ijọba Apapọse on pelu Premier ilẹ Hausa Alhaji Sir Ahmadu Bello, Oloye Sardauna Ṣokoto ni yio jumo gba ijoye ilu Oyinbo kan ti 'o mbo wa ṣe awuyewuye isodi ijoba iṣ'akoso ara eni nilẹ Hausa.

Sardauna ati Balewa, Ranka dẹ-de, ẹ ku ipalẹmọ.

## Kabo O Oloye Sowole.

Lọjọ Alaruba, 6th oṣu May 1959 ni Oloye M. S. Ṣowole, ẹniti o ti lọ ṣe aṣoju ijoba Iwo-Orun nilu Oyinbo ba oko oju omi pada wa sile fun isinmi oṣu mẹfa. Oloye Awolowo ati Ọgbẹni J. E. Imokunẹdẹ ni nwọn jijọ lọ pade rẹ.

### ỌKỌ TITUN DE FUN N.P.A.

Awọn Olotu ile iṣẹ Nigeria Ports Authority gbe ọkọ titun meji de lati fi kun awọn ọko meji ti nwon ti ni ri. Oruko awon oko mejeji na ni Delphin ati Barbaruda.




## IJUMU PROGRESSIVE UNION CONFERENCE

(Cotinued from page 5)

ters. A total sum of £2000 has been granted by the Northern Regional Government to implement the two Buildings.

National Publicity Secretary,
Ilesha.

Before the two days Conference of the Ijumu Progressive Union ended at Ilesha recently the following National Officers were appointed for the first time sinecs the Union was formed at about 36 years ago.

Patrons:- Chief Obajemu of Ikoyi, Chief Olugbede of Gbede and the Oba of Ogele.

National President Mr. J. O. Olowolusi, First Vice President Mr. S. A. Ajayi (N.R.A.) Second Vice National President Mr. S. O. Olundi National General Secretary Mr. S. O. Omolawun, Assistant National General Secretary Mr. S. O. Oguntobi National Publicity Secretary Mr. Michael B. Asaju, Tresurer Mr. T. A. Ibikunle, Financial Sec. Mr. Adeyemi Ajayi, Auditors Messers H. O. Olupeka and R. O. Eniwaiye. Legal Advicer Mr. Olu Johnson.

## OMIRAN MEJI YIO FARABARA WO

A gbọ irohin wipe Ọkunrin omiran kan ti oruko re nje Kiilwe Nwachuku ẹniti ti tobi re tewon to Ọdunrun-le-mejileiogbon iwon (332 Ibs) ni a gbọ wipe o mbo nilu Eko lati wa ba Ọkunrin omiran miran to pe ni ija pade, ki nwon si dan agbara arawon wo. Oruko omiran keji ni Julius Way. Sugbon o tun sọ wipe lehinti awon mejeji ba ti fi oju aje kan oniso tan, on yio tetare koja lo sile Aganyin, Ghana.

**Kere o !**

Ati ni orisirisi ogun German to ṣẹṣẹ de, fun oniruru aisan tọkunrin tobinrin. Tete wa ra tire ki o to tan.

J. A. AJAO BROTHERS
MEDICINE STORES
7 Egerton Road Lagos

## Agbagba Mejo Ja Okan Ko Jebi Okan Ko Jare

Lati ọwọ ẸSỌ

Iya iyawo Yanmu-yanmu wa ki oko omo rẹ, nigbati o npada lo sile, yanmuyanmu pa ese re de oju ona. Bi awon mejeji ti nlo, nwon fẹ wo inu igbo kan bayi, ano yanmu yanmu so wipe ha ! igbo yi ma tobi o, on ko le nikan la a ja.

Yanmu-yanmu dahun wipe haba lati ojo yi iwo koiti mo mo mi ni okunrin ! Wo, apa mi otun yi gba igba kunmo ẹsẹ mi osi gba igba atori, ẹhin mi yi gba igba ẹkẹsẹ.

Ọro yi ni Yanmuyanmu nso fun ano re lowo ti Ọkẹre gbo lo ba ku si ẹrin. O rẹrin titi eyin ẹnu rẹ ti o njẹ bo silẹ Bi eyin na ti bo sile o ṣe konge furọ Ẹta nitoripe nigbati Ẹta yagbẹ tan idi bẹrẹ si ta a lo ba tagiri ti o si nsalọ

Ere ti o ti nwa onjẹ lati iwon ọjọ mẹta ti ko ri wa la ẹnu silẹ boya ekute kan yio ṣebi iho ni yio si ko wo Bi Ẹta ti nsare lo o tẹse bo ejo lẹnu, ejo si panude mo nibiti Ẹta ti nja ẹsẹ Ẹta kan mọ enu ejo.

Ejo rope, bi on ba duro nigbangba lati ma jẹ esẹ ẹran na ẹgbẹ on ti o lagbara ju on yio wa ba on jẹ nitorina o pinnu lati lọ jẹ ninu iho Ẹjo na ri iho kan nitosi, ṣamo-ṣamo iho Okete ni, ejo ra wo o

Bi Okete ti gbe oju soke ti o ri i pe ejo lo mbo yi o ni ha ọrọ buruku ko ba Ikun nile lo ba gba odikeji yọ, o si nsalọ Ẹiye Gunugun ti o njẹ igbẹ lọwo ninu papa ti o si ri Okete ti ko njade ọsan ti o nsare bọwa, Gunugun wipe kinla, bi ko ba si ohun ti o nle agbalagba ko ma ni sare asalagun bayi, nitorina on ko ni jẹki nkan ti o nle Okete jade nilẹ yi wa fọwọ ba on Bẹni Gunugun ba gbe gbe igbe ti o njẹ o di ori Iroko.

Iroko dahun wipe, ha ẹgbin idalẹ wo ni eyi ? Lati ọjọ ti ọba ti le on sibin, iwọsi kan ko tale on ri bẹ, bo kan oro ti ao fi dobale fun keferi ki a kuku rọju ku lo tọ. Ni igi iroko ba yẹri o si wo lule lo ba fọ ẹnyin Awo.

Ibẹ ni Awo ba tẹ igbe bonu lo nkigbe oro oro oro Nigbati o ṣe oro na de ọdọ ọba ẹniti o ranṣe pe awo o si bere wipe kini ohun ti o ṣe e.

Awo rojọ wipe jẹjẹ ni on gbe eyin silẹ ti igi iroko, lo te won fo oro oro oro Ọba ranṣe lo pe igi iroko o bere ejo Iroko dahun pe Kabiyesi ọba lati ọjọ ti a ti lẹ on ẹgbin ati iwosi kan ko gun on ri Gunugun lo fe gbe igbe ba le on lori, eyi nidi re ti on fi yeri on ko si mọ pe ẹyin Awo wa nibe Ọba dahun pe ko jebi. Ki nwọn lọ pe Ẹiye Gunugun na wa.

(Koiti pari)

## Ojo Isinmi Awon Imale, Ijo Aguda Yio Gba Lori Ikilo

Olori ijọ Aguda Dr. Leo. H. Taylor, Archbishop ti ilu Eko sọ si oro ojo isinmi ti Ijo awon ẹlẹsin imale ti awon igbimo Town Council Eko ṣe ipinnu le lori wipe ki nwon kesi Ọga Olotu ẹko tilu Eko ki o ṣe ofin le ojo isinmi awon Musulumi lori ki gbogbo ilewe ma ti ilẹkun won iba ṣe kiriyo tabi ẹlẹsin miran.

Archbishop Aguda so wipe oro ṣiṣe ojo isinmi ti Imale ko ni lati je tulasi fun Ijo miran, nitoripe Aguda na ni ojo isinmi tirẹ ti awon ko je bere bi elesin miran tẹle tabi ko tele, gegebi irufe "Ọjo awon enia mimo".

Bi igbimo Town Council ti Eko ba kannipa pe gbogbo ilewe ti o ba wa labẹ re ni lati ti ilẹkun ni ojo isinmi awon Imale Ijo Aguda yio gba nitori ofin lati ti ilekun ilewe won sugbon ey ni ki iṣe wipe Aguda npa ojo isinmi awon Imale mo.


# M.B.T.

(MAGIC BLOOD TONIC)



Iná dé, òkùnkùn paradà. M.B.T. dé, òkùnrùn fò lọ. Ẹ̀jẹ̀ dúdú sáré òyì pòṣèṣè. Àlá búburú wọ̀gbó. Àìlèsùn rẹ̀hìn-ẹ̀kùn. M.B.T. fògùn ẹ̀jẹ̀ ti nmú ni jẹun b'ìkàn, amú ni yàgbẹ́ bí ọ̀kùn, amú ni tọ̀ bí àkẹ̀rẹ́. Abiwẹ́rẹ́ fàbọyún, agbẹ̀jẹ̀ di fawọn abiyamọ. Ahọ́n-dúdú, ẹsẹ̀-wíwú ati àìyà-jíjá ko si ẹ́nìti nìo o.

4/6d pẹ̀lú 1/6d owó-ọkọ̀.

ARADAN STORES P.O.Box EBUTE-METTA.


## Ibukun Ni Iranti Olododo



Ẹniti a nwo yi ni Ejonigboro, Herbert Samuel Heelas Macaulay C. E. ti o ti di Ologbe ẹniti o jẹ wipe o fi tọkan-tọkan ja fun ire ati anfani ilẹ Nigeria, ọn kanna yi lo da ẹgbẹ National Democratic Party silẹ ninu ọdun 1923.

O ku file aiye sile ni ọjọ keje oṣu May, 1946.

O wẹ okun-wẹ ọsa, o si mu ọpa bọ wa sile, oju gbogbo wa lo ṣe.

Maṣe jẹ ọkun, maṣe jẹ ekolo, Sunre!

## KO SIBITI EṢE KOSI !

ACCRA. Ijọba ilẹ Ghana ti gbe ofin kan jade ninu ofin gbigba a w ọ n Ijoye, wipe Oloye NII Adjetey Ansah, Keji ko gbọdọ ṣe bi Oloye Tema Mantse mọ.

Ijọba si wipe nitori awọn enia ti ko ni ifẹ si Oloye na mọ ni awọn ṣe fi ofin da duro. Eyi fihan pe ko sibiti nwọn ki igbe rọ Oloye l'oye.

## OMOLOLU D'O-LOGBE!

Gbuke l'agbo wipe Ọgbeni C. A. Omololu ti o je Baba-egbe Island Club l'Eko s'alaisi ni ile iwosan Creek Hospital ni ojo Alamisi, ojo keje oṣu May, 1959. Ologbe Omololu yi ni eni ti o ṣe akonije awon osere ilẹ wa lo si ilu Cadiff lasiko ere idaraya ti ilẹ Gẹsi ṣe kọja.

Ologbe Omololu ẹni rere yi fi omokunrin meji silẹ. ọkini Ọgbeni O. O Omololu ti ise Oga akowe agba nile isẹ. Olotu ijoba apapọṣe ati ekeji ni Dọkita Adewale Omololu ti University College Hospital nilu Ibadan.

Ni Satide oni ni nwon yio sinku rẹ.


E MA KA IWE IROHIN ELETI - OFE

LỌSỌSẸ OKUN FUN IROHIN ALADUN


Printed & Published by The Union Printing Publishing Company 28, Kosoko Street, Lagos P. O. Box 467 phone 23370